# Ijakadi Laarin Satani Ati KRISTI

- Isẹgun agbayanu wa lori awọn ẹmi okunkun
- Mase sin Ẹlẹtan, Satani tabi awọn ẹmi aimọ
- Iparun ayeraye ni o wa fun gbogbo ẹnikẹni ti o ba gba "Ami Eranko Naa" si ọwọ tabi si iwaju ori wọn, ki wọn ba lee ta tabi ra.

Akojọpọ lati ọwọ Watson Goodman

Ọfẹ—Kii se fun tita

# IFAGAGBAGA SATANI ATI KRISTI

Satani, ti a se apejuwe rẹ ninu Ọrọ Ọlọrun gẹgẹbi "Ọmọ—alade aye yi," ni ọta atayebaye Ọlọrun ati ẹda Ọlọrun ti o ga julọ—eniyan. Awa eniyan ẹlẹran ara wa ni ibudo ijagun ti o gbona girigiri. Ogun naa nlọ laarin KRISTI ati Satani. A nilati yan tani ninu awọn mejeeji ti yoo jẹ ọga wa titi lae, KRISTI Ẹlẹda—Ẹniti ise Immanuẹli (Ọlọrun wa pẹlu wa)—tabi Satani, ẹniti a da—ẹniti ise ọmọ alade gbogbo isọtẹ si Ọlọrun, Nipasẹ iku ati ajinde Rẹ KRISTI gba isẹgun ti o peye fun gbogbo iye awọn ti yoo ba gba A gbọ nitootọ.

Satani ngbidanwo ni ogunlọgọ ọna lati tan eniyan ati lati sii dari. Isin ni ohun ti o ga julọ ti o wa nibẹ. KRISTI, Ẹlẹda wa, ni o ni ẹtọ si gbogbo isin wa. Ẹniti a ba nsin ni a maa n faramọ. Igbidanwo Satani ti o kẹhin lati gba isakoso eniyan ni gbogbo agbaye duro le: (1) Ominira kuro lọdọ Ọlọrun. (2) Igbọran si awọn ẹmi esu, (3) Sisin "ẹmi-ẹsẹ ni". (4) Sisin "ere" rẹ ati (5) ami ni ara ti eniyan nilo lati ta ati lati ra. Sọra fun awọn ohun gbogbo wọnyi!

—Watson Goodman (1920-2002)

### *Ọlọrun da Lusiferi fun ipo ti o ga pupọ ni ọrun*

Bayi li Oluwa Ọlọrun wi, Iwọ fi edidi dí iye na, o kún fun ọgbọ́n, o si pé li ẹwà. Iwọ ti wà ni Edeni ọgbà Ọlọrun; oniruru okuta iyebiye ni ibora rẹ, sardiu, topasi, ati diamondi, berili, oniksi, ati jasperi, safire, emeraldi, ati karbunkili, ati wura: iṣẹ ìlu rẹ ati ti fère rẹ li a pèse ninu rẹ li ọjọ ti a dá ọ.

### *O sun mọ itẹ Ọlọrun*

Iwọ ni kerubu ti a fi ororo yàn ti o si bò; emi si ti gbe ọ kalẹ: iwọ wà lori oke mimọ́ Ọlọrun; iwọ ti rìn soke rìn sodò lãrin okuta iná.

### *A daa ni pipe*

Iwọ pé li ọnà rẹ lati ọjọ ti a ti dá ọ, titi a fi ri aiṣedēde ninu rẹ.

### *Ọlọrun ti ẹsẹ jade*

Nitori . . . òwo rẹ, nwọn ti fi iwà ipa kún ãrin rẹ, iwọ si ti ṣẹ̀: nitorina li emi o ṣe sọ ọ nù bi ohun ailọ̀wọ kuro li oke Ọlọrun: emi o si pa ọ run, iwọ kerubu ti o bò, kuro lãrin okuta iná. —Esekiẹli 28:12b-16

Orin Dafidi 5:4, 5

Nitori ti iwọ kì iṣe Ọlọrun ti inu rẹ̀ ndun si ìwa buburu: Bẹ̄ni ibi kò le ba ọ gbe. Awọn agberaga kì yio le duro niwaju rẹ: Iwọ korira gbogbo awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ.

Owe 16:18

Igberaga ni iṣaju iparun; agidi ọkàn ni iṣaju iṣubu.

Esekiẹli 28:17-19

Ọkàn rẹ gbe soke nitori ẹwà rẹ; o ti ba ọgbọ́n rẹ jẹ nitori dídan rẹ; emi o bì ọ lulẹ, emi o gbe ọ kalẹ niwaju awọn ọba, ki nwọn ba le wò ọ.

### *Atubọtan Ọlọtẹ*

Iwọ ti bà ibi-mimọ́ rẹ jẹ nipa ọ̀pọlọpọ aiṣedēde rẹ, nipa aiṣedēde òwo rẹ; nitorina emi o mu iná jade lati ārin rẹ wá, yio jó ọ run, emi o si sọ ọ di ẽru lori ilẹ, loju gbogbo awọn ti o wò ọ. Gbogbo awọn ti o mọ̀ ọ lārin awọn orilẹ-ède li ẹnu o yà si ọ: iwọ o jẹ ẹ̀ru, iwọ kì yio si si mọ́ lailai.

### *Gbogbo Ẹda Nilati Wa Ni Itẹriba Si Ẹlẹda*

Orin Dafidi 100:2, 3

Ẹ fi ayọ̀ sin Oluwa: Ẹ wá ti ẹnyin ti orin si iwaju rẹ̀. Ki ẹnyin ki o mọ̀ pe Oluwa, on li Ọlọrun: On li o dá wa, tirẹ̀ li awa; awa li enia rẹ̀, ati agutan papa rẹ̀.

Orin Dafidi 111:10; 112:1

Ìbẹru Oluwa ni ipilẹṣẹ ọgbọ́n: Oye rere ni gbogbo awọn ti npa ofin rẹ̀ mọ́ ni: Iyin rẹ̀ duro lailai. Ẹma yìn Oluwa. Ibukún ni fun ẹniti o bẹ̀ru Oluwa, ti inu rẹ̀ dùn jọjọ si ofin rẹ̀.

### *Ifẹ rẹ ti o lodi si ifẹ Ọlọrun*

Isaiah 14:12-19a

Bawo ni iwọ ti ṣe ṣubu lati ọrun wá, Iwọ Lusiferi, irãwọ owurọ! bawo li a ti ṣe ke ọ lu ilẹ, iwọ ti o ti ṣẹ awọn orilẹ-ède li apa! Nitori iwọ ti wi li ọkàn rẹ pe, Emi o goke lọ si ọrun, emi o gbe itẹ mi ga kọja iràwọ Ọlọrun: emi o si joko lori oke ijọ enia ni iha ariwa: Emi o goke kọja giga awọsanma: emi o dabi ọga-ogo jùlọ.

### *Iparun isẹ rẹ l'aye*

Ṣugbọn a o mu ọ sọkalẹ si ipòokú, si iha ihò. Awọn ti o ri ọ yio tẹjumọ ọ, nwọn o si ronu rẹ pe, Eyi li ọkunrin na ti o mu aiye warìri, ti o mu ilẹ ọba mìtiti; Ti o sọ aiye dàbi agìnju, ti o si pa ilu rẹ run; ti kò dá awọn ondè rẹ silẹ lati lọ ile?

### *Ọ jẹ ẹni irira si Ọlọrun*

Gbogbo ọba awọn orilẹ-ède, ani gbogbo wọn, dubulẹ ninu ogo, olukuluku ninu ile rẹ. Ṣugbọn iwọ li a gbe sọnù kuro nibi iboji rẹ bi ẹka irira, bi aṣọ awọn ti a pa, awọn ti a fi idà gun li agunyọ, ti nsọkalẹ lọ si ihò okuta.

II Tessalonika 2:3b, 4

. . . ki a si fi ẹni ẹ̀ṣẹ nì hàn, ti iṣe ọmọ ègbé; Ẹniti nṣòdì, ti o si ngbé ara rẹ ga si gbogbo ohun ti a npè li Ọlọrun, tabi ti a nsin; tobẹ ti o joko ni tẹmpili Ọlọrun, ti o nfi ara rẹ hàn pe Ọlọrun li on.

### *Bẹrẹ lati ori Lusiferi*

*(Wo awọn "Emi o" marun ti Lusiferi ninu Iwe Isaiah 14:13, 14 ni oju ewe 3.)*

O si wi fun wọn pe, Emi ri Satani ṣubu bi manamana lati ọrun wá. —Luku 10:18

### *Ninu awọn angẹli ti o tẹle Satani*

II Peteru 2:4

. . . .Ọlọrun kò dá awọn angẹli si ti nwọn ṣẹ, ṣugbọn o sọ wọn si isalẹ ọrun apadi, o si fi wọn sinu ọgbun òkunkun biribiri awọn ti a pamọ́ de idajọ.

### *Ninu awọn eniyan ti Satani lee tan jẹ*

I Timoteu 3:6

Ki o má jẹ ẹni titun, kí o má bã gbéraga, ki o si ṣubu sinu ẹbi Èṣu.

### *Satani gba isakoso l'ori eniyan*

II Peteru 2:19b

. . . nitori ẹniti o ba ṣẹgun ẹni, on na ni isi sọ ni di ẹrú.

### *Ifẹ Ẹnikansoso ni o nilati sẹ ni ọrun—Ifẹ Ọlọrun ti o peye*

Romu 12:2

Ki ẹ má si da ara nyin pọ̀ mọ́ aiye yi: ṣugbọ́n ki ẹ parada lati di titun ni iro-inu nyin, ki ẹnyin ki o le ri idi ifẹ Ọlọrun, ti o dara, ti o si ṣe itẹwọgbã, ti o si pé.

Ẹgbẹẹgbẹrun ifẹ eniyan ni yoo wa ni ọrun apaadi, wọn yoo maa korira ara wọn titi ayeraye.

Deuteronomi 5:6, 7

Emi li OLUWA Ọlọrun rẹ, ti o mú ọ lati ilẹ Egipti, lati oko-ẹrú jade wá. Iwọ kò gbọdọ ní ọlọrun miran pẹlu mi!

I Kronika 16:29

Ẹ fi ogo fun Oluwa ti o yẹ fun orukọ rẹ̀: mu ọrẹ wá, ki ẹ si wá siwaju rẹ̀; ẹ sin Oluwa ninu ẹwà ìwamimọ́.

Matteu 4:10

Nigbana ni Jesu wi fun u pe, Pada kuro lẹhin mi, Satani: nitori a kọwe rẹ̀ pe, Oluwa Ọlọrun rẹ ni ki iwọ ki o foribalẹ fun, on nikanṣoṣo ni ki iwọ mã sìn.

Ifihàn 19:10a

Mo si wolẹ li ẹsẹ rẹ̀ (angeli naa) lati foribalẹ fun u. O si wi fun mi pe, Wò o, máṣe bẽ: iranṣẹ ẹlẹgbẹ rẹ li emi, ati ti awọn arakunrin rẹ ti nwọn di ẹrí Jesu mu: foribalẹ fun Ọlọrun.

Orin Dafidi 95:6

Ẹ wá, ẹ jẹ ki a wolẹ, ki a tẹriba: Ẹ jẹ ki a kunlẹ niwaju Oluwa, Ẹlẹda wa. ***(Ka Gen. 1:27.)***

## *Awọn ti a ti tanjẹ nsin Ọlọtẹ*

Ifihàn 13:3b, 4a

. . . . gbogbo aiye si fi iyanu tẹle ẹranko na. Nwọn si foribalẹ fun ikõko na nitori o ti fun ẹranko na ni ọla: nwọn si foribalẹ fun ẹranko na.

### *Satani ati awọn ẹmi aimọ n fẹ ki a sin wọn*

Matteu 4:8, 9

Èṣu gbé e lọ si ori òke giga-giga ẹwẹ, o si fi gbogbo ilẹ ọba aiye ati gbogbo ogo wọn hàn a; O si wi fun u pe, Gbogbo nkan wọnyi li emi ó fifun ọ, bi iwọ ba wolẹ, ti o si foribalẹ fun mi.

Ifihàn 9:20

Ṣugbọn awọn enia iyokù, ti a kò si ti ipa arun wọnyi pa, kò si ronupiwada iṣẹ ọwọ́ wọn, ki nwọn ki o máṣe sìn awọn ẹmi èṣu, ati ere wura, ati ti fadaka, ati ti idẹ, ati ti okuta, ati ti igi mọ́, awọn ti kò le riran, tabi ki nwọn gbọran, tabi ki nwọn rìn.

### *Ọlọrun pa iru awọn olusin bẹẹ run*

Ifihàn 16:2b ati 20:13b, 14

. . . egbò kikẹ ti o si dibajẹ si dá awọn enia ti o ni àmi ẹrankọ na, ati awọn ti nforibalẹ fun aworan rẹ. . . . a si ṣe idajọ wọn olukuluku gẹgẹ bi iṣẹ wọn. Ati ikú ati ipo-okú li a si sọ sinu adagun iná. Eyi ni ikú keji.

Isaiah 42:8

Emi li Oluwa: eyi ni orukọ mi: ogo mi li emi kì yio fi fun ẹlòmiran, bẽni emi kì yio fi iyìn mi fun ere gbigbẹ́.

# AWỌN ANGẸLI KRISTI ATI AWỌN ANGẸLI SATANI

***Awọn Angẹli Oluwa lagbara ju awọn angẹli satani ti o ti subu lọ***

Orin Dafidi 103:20

Ẹ fi ibukún fun Oluwa, ẹnyin angẹli rẹ̀, ti o pọ̀ ni ipa, ti nṣe ofin rẹ̀, ti nfi eti si ohùn ọ̀rọ rẹ̀.

Ifihàn 12:7, 8a

Ogun si mbẹ li ọrun: Mikaeli ati awọn angẹli rẹ̀ ba ikõko na jàgun; ikõko si jàgun ati awọn angẹli rẹ̀. Nwọn kò si le ṣẹgun.

***Awọn Angẹli mimọ Ọlọrun n se isẹ iransẹ fun, wọn si n dabobo awọn eniyan Oluwa***

Heberu 1:14

Ẹmí ti njiṣẹ ki gbogbo wọn iṣe, ti a nran lọ lati mã jọsin nitori awọn ti yio jogun igbala.

Orin Dafidi 91:11

Nitoriti yio fi aṣẹ fun awọn angẹli rẹ̀ nitori rẹ, lati pa ọ mọ́ li ọ̀na rẹ gbogbo.

***Awọn ti o subu (awọn ẹmi esu, awọn ẹmi aimọ) pinnu lati mu eniyan lọ si ọrun apaadi***

Luku 11:26b

. . . o si mu ẹmi meje miran ti o buru jù on tikararẹ̀ lọ . . . .

I Timoteu 4:1

Ṣugbọn Ẹmí ntẹnumọ ọ pe, ni igba ikẹhin awọn miran yio kuro ninu igbagbọ́ nwọn o mã fiyesi awọn ẹmí ti ntanni-jẹ, ati ẹkọ́ awọn ẹmí èṣu.

# 8 ẸNI ATI OHUN TI SATANI KORIRA NI PATAKI

***Eniyan, A daa ni Aworan Ọlọrun***

Luku 9:42

Bi o si ti mbọ̀, ẹmi èṣu na gbé e ṣanlẹ, o si nà a tantan. Jesu si ba ẹmi aimọ́ na wi, o si mu ọmọ na larada, o si fà a le baba rẹ̀ lọwọ.

***Awọn Idile—Ibukun Ọlọrun***

Genesisi 12:3

Emi o bukun fun awọn ti nsúre fun ọ, ẹniti o nfi ọ ré li emi o si fi ré; ninu rẹ li a o ti bukun fun gbogbo idile aiye.

***Kristi (Ọlọrun ninu ara), Pẹlu igbala ninu Ara Rẹ ati Ẹjẹ mimọ Rẹ***

Matteu 2:16

. . . Herodu . . . binu gidigidi, o si ranṣẹ, o si pa gbogbo awọn ọmọkunrin ti o wà ni Betlehemu . . . lati awọn ọmọ ọdún meji jalẹ gẹgẹ bi akokò ti o ti bere lẹsọlẹsọ lọwọ awọn amoye na.

***Ọrọ Ọlọrun—Satani nse atako***

Genesisi 3:1b, 4

Õtọ li Ọlọrun wipe? . . . Ejò na si wi fun obirin na pe, Ẹnyin ki yio ku ikú kikú kan.

***Orilẹ-ede ti Ọlọrun yan, Israeli***

Ifihàn 12:13

Nigbati ikõko na ri pe a lé on lọ si ilẹ aiye, o ṣe inunibini si obirin ti o bí ọmọkunrin na.

***Awọn Onigbagbọ ti a bi nipa Ẹmi***

I Peteru 5:8

. . . Èṣu, ọtá nyin, . . . nrìn kãkiri, o nwá ẹniti yio pajẹ kiri.

### *O nse ayederu ami Oniunkan*

Ifihàn 22:3, 4

Ègún kì yio si si mọ́: itẹ́ Ọlọrun ati ti Ọdọ-Agutan ni yio si ma wà nibè; awọn iranṣẹ rẹ̀ yio si ma sìn i: Nwọn o si mã ri oju rẹ̀; orukọ rẹ̀ yio si mã wà ni iwaju wọn.

***(Wo ayederu Satani ni oju ewe 35)***

### *O nyi ihinrere po pẹlu irọ*

Galatia 1:6, 7

Ẹnu yà mi nitoriti ẹ tete kuro lọdọ ẹniti o pè nyin sinu ore-ọfẹ Kristi, si ihinrere miran: Eyiti kì iṣe omiran; bi o tilẹ ṣe pe awọn kan wà ti nyọ nyin lẹnu, ti nwọn si nfẹ yi ihinrere Kristi pada.

### *O nse ayederu awọn iransẹ Ọlọrun*

Nitori irú awọn enia bẹ̃ li awọn eke Aposteli, awọn ẹniti nṣiṣẹ ètan, ti npa ara wọn dà di Aposteli Kristi. Kì si iṣe ohun iyanu; nitori Satani tikararẹ̀ npa ara rẹ̀ dà di angẹli imọlẹ. —II Korinti 11:13, 14

### *Awọn Isẹ iyanu Ọlọrun yatọ si isẹ iyanu eke*

II Tess. 2:9; Ifi. 13:13; 19:20

***Gẹgẹbi Kristi ti se ngba isakoso Ẹniti O ba nsin ni otitọ, bẹẹni Satani naa ngba isakoso Ẹni ti o ba sin tabi awọn ọlọrun rẹ.***

Oluwa Ọlọrun wa, awọn oluwa miran lẹhin rẹ ti jọba lori wa . . . .
—Isaiah 26:13a

I Johannu 5:21

Ẹnyin ọmọ mi, ẹ pa ara nyin mọ́ kuro ninu oriṣa. Amin.

Eksodu 20:3-5a

Iwọ kò gbọdọ lí ọlọrun miran pẹlu mi. Iwọ kò gbọdọ yá ere fun ara rẹ, tabi aworan ohun kan ti mbẹ loke ọrun, tabi ti ohun kan ti mbẹ ni isalẹ ilẹ, tabi ti ohun kan ti mbẹ ninu omi ni isalẹ ilẹ. Iwọ kò gbọdọ tẹ̀ ori ara rẹ ba fun won, bẹ̃ni iwọ kò gbọdọ sìn wọn.

***Awọn ọlọrun miran ohun irira si Ọlọrun, Ifi - eniyan - rubọ jẹ ohun aigbọdọ se***

Deuteronomi 12:2 ati 30a, 31

Ki ẹnyin ki o run ibi gbogbo wọnni patapata, nibiti awọn orilẹ-ède nì, ti ẹnyin o gbà, nsìn oriṣa wọn, lori òke giga, ati lori òke kekeè, ati labẹ igi tutù gbogbo: . . . Ma ṣọ́ ara rẹ ki iwọ má ba bọ́ si idẹkùn ati tẹle wọn lẹhin, lẹhin igbati a ti run wọn kuro niwaju rẹ; . . . Iwọ kò gbọdọ ṣe bẽ si OLUWA Ọlọrun rẹ; nitoripe gbogbo ohun irira si OLUWA, ti on korira, ni nwọn ti nṣe si awọn oriṣa wọn; nitoripe awọn ọmọkunrin, ati awọn ọmọbirin wọn pẹlu ni nwọn nsun ninu iná fun oriṣa wọn.

Mika 6:7b

Emi o ha fi . . . iru-ọmọ inu mi fun ẹ̀ṣẹ ọkàn mi?

***Ẹjẹ Kristi n wẹ ẹsẹ Nu***

***Sisin orisa jẹ isiwere***

Awọn ẹniti o yi otitọ Ọlọrun pada si eke, nwọn si bọ, nwọn si sìn ẹda jù Ẹlẹda lọ, ẹniti iṣe olubukun titi lai. Amin. —Romu 1:25

Orin Dafidi 115:3-8

Ṣugbọn Ọlọrun wa mbẹ li ọrun: O nṣe ohun-kohun ti o wù u. Fadaka ati wura li ere wọn, iṣẹ ọwọ enia. Nwọn li ẹnu ṣugbọn nwọn kò sọ̀rọ: Nwọn li oju, ṣugbọn nwọn kò riran. Nwọn li eti, ṣugbọn nwọn kò gbọran: Nwọn ni imu, ṣugbọn nwọn kò gbõrun. Nwọn li ọwọ, ṣugbọn nwọn kò lò o: Nwọn li ẹsẹ, ṣugbọn nwọn kò rìn: Bẽni nwọn kò sọ̀rọ lati ọfun wọn jade. Awọn ti nṣe wọn dabi wọn; Bẽli olukuluku ẹniti o gbẹkẹle wọn.

***Sisin orisa jasi sisin Esu***

I Korinti 10:14b ati 20

. . . ẹ sá fun ibọriṣa. . . . Ṣugbọn ohun ti mo nwi nipe, ohun ti awọn Keferi fi nrubọ, nwọn fi nrubọ si awọn ẽmi èṣu, kì si iṣe si Ọlọrun: emi kò si fẹ ki ẹnyin ki o ba awọn ẹmi èṣu ṣe ajọpin.

***Ijiya fun sisin orisa***

Ifihàn 21:8b

Abọriṣa . . . ni yio ní ipa tiwọn ninu adagun ti nfi iná ati imi-ọjọ jò: eyi ti iṣe ikú keji.

I Korinti 6:9b, 10b

Kì a má tàn nyin jẹ: kì iṣe awọn àgbere, tabi awọn abọriṣa, . . . ni yio jogún ijọba Ọlọrun.

***Ọlọrun pa awọn orilẹ-ede run fun sisin orisa—ko gbọdọ si orisa ninu ile Rẹ!***

Deuteronomi 7:24-26a

On o si fi awọn ọba wọn lé ọ lọwọ, iwọ o si pa orukọ wọn run kuro labẹ ọrun: kò sí ọkunrin kan ninu wọn ti yio le duro niwaju rẹ, titi iwọ o fi run wọn tán. Ere finfin orișa wọn ni ki ẹnyin ki o fi iná jó: . . . nitoripe ohun irira ni si OLUWA Ọlọrun rẹ: Bẽni iwọ kò gbọdọ mú ohun irira wá sinu ile rẹ, ki iwọ ki o má ba di ẹni ifibú bi rẹ̀ . . . .

***Eese ti ọpọ eniyan ni orilẹ-ede ti Ọlọrun yan fi kun fun ẹmi esu ni akoko isẹ iransẹ Kristi? Awọn babanla wọn sin esu.***

Orin Dafidi 106:36, 37 ati 40

Nwọn si sìn ere wọn: ti o di ikẹkun fun wọn. Nitõtọ nwọn fi ọmọkunrin wọn ati ọmọbirin wọn rubọ si orișa. . . . Nitorina ni ibinu Oluwa șe ràn si awọn enia rẹ̀, o si korira awọn enia ini rẹ̀.

Ẹksodu 20:5

Iwọ kò gbọdọ tẹ̀ ori ara rẹ ba fun wọn, bẽni iwọ kò gbọdọ sìn wọn: nitori emi li OLUWA Ọlọrun rẹ, Ọlọrun owú ni mi, ti mbẹ̀ ẹ̀sẹ awọn baba wò lara awọn ọmọ, lati irandiran kẹta ati ẹkẹrin ninu awọn ti o korira mi.

### Ẹksodu 22:18
Iwọ kò gbọdọ jẹ ki ajẹ́ ki o wà lãye.

### Lefitiku 19:31
Máṣe yipada tọ̀ awọn abõkusọ̀ro, bẽni ki ẹnyin ki o má si ṣe wá oṣo kiri, lati fi wọn bà ara nyin jẹ́: Emi li OLUWA Ọlọrun nyin.

### Mika 5:12
Emi o si ke iwà ajẹ kuro lọwọ rẹ: iwọ kì yio si ni alafọ̀ṣẹ mọ.

### I Samuẹli 15:23
Nitoripe iṣọtẹ dabi ẹ̀ṣẹ ajẹ, ati agidi gẹgẹ bi ìwa buburu ati ibọrisa. Nitoripe iwọ kọ̀ ọ̀rọ Oluwa, on si kọ̀ ọ li ọba.

### Deuteronomi 18:9-12
Nigbati iwọ ba dé ilẹ na ti OLUWA Ọlọrun rẹ fi fun ọ, ki iwọ ki o máṣe kọ́ ati ṣe gẹgẹ bi ìwa irira awọn orilẹ-ède wọnni. Ki a máṣe ri ninu nyin ẹnikan ti nmu ọmọ rẹ̀ ọkunrin, tabi ọmọ rẹ̀ obirin là iná já, tabi ti nfọ̀ afọ̀ṣẹ, tabi alakiyesi ìgba, tabi aṣefàiya, tabi ajẹ́, tabi atuju, tabi aba-iwin-gbìmọ, tabi oṣó, tabi abõkusọ̀rọ. Nitoripe gbogbo awọn ti nṣe nkan wọnyi irira ni si OLUWA: ati nitori irira wọnyi ni OLUWA Ọlọrun rẹ ṣe lé wọn jade kuro niwaju rẹ.

Abokusọrọ: Sise asọtẹlẹ ọjọ iwaju nipa pipe ẹmi awọn ti o ti ku; pipe ogede.

# SISỌ ASỌTẸLẸ ỌJỌ IWAJU NIPA IRANLỌWỌ ẸMI ESU

### *Ọlọrun lodi si aworawọ, oso ati igbẹrẹ*

**Lefitiku 19:26 ati 28**

Ẹnyin kò gbọdọ jẹ ohun kan ti on ti ẹ̀jẹ: bẽli ẹnyin kò gbọdọ ṣe afọṣẹ, tabi huwa ajẹ́. . . . Ẹnyin kò gbọdọ sín gbẹ́rẹ kan si ara nyin nitori okú, bẽli ẹnyin kò gbọdọ kọ àmi kan si ara nyin: Emi li OLUWA.

**Jeremiah 27:9a**

Nitorina ẹ máṣe fi eti si awọn woli nyin, tabi si awọn alafọṣẹ nyin, tabi si awọn alála, tabi si awọn oṣo nyin, tabi awọn ajẹ nyin.

**Malaki 3:5b**

. . . Emi o si ṣe ẹlẹri yiyara si awọn oṣó, ati . . . awọn panṣaga, ati si awọn abura eké . . . .

**Sekariah 10:2**

Nitori awọn oriṣa ti nsọ̀rọ asan, awọn alafọṣẹ si ti ri eké, nwọn si ti rọ́ alá eké; nwọn ntù ni ni inu lasan, nitorina nwọn ba ti wọn lọ bi ọwọ́ eran; a ṣẹ wọn nişẹ, nitori darandaran kò si.

### *Gbẹkẹle Olusọ—Aguntan Tootọ*

**Johannu 14:1**

Ẹ maṣe jẹ ki ọkàn nyin dàru: ẹ gbà Ọlọrun gbọ́, ẹ gbà mi gbọ́ pẹlu.

Afọṣẹ: Sisọ ọjọ iwaju tabi ohun ti o pamọ nipa ọna eke.

Oso: Biba awọn ẹmi esu lo.

### *Sise afọsẹ pẹlu ẹmi awọn oku (alujọọnu)*

Isaiah 8:19a

Nigbati nwọn ba si wi fun nyin pe, Ẹ wá awọn abõkusọ̀rọ, ati awọn oṣó ti nke, ti nsi nkùn, kò ha yẹ ki orilẹ-ède ki o wá Ọlọrun won?

### *Lilo ẹya ara tabi ere*

Esekieli 21:21

Nitori ọba Babiloni duro ni iyàna, lori ọ̀na meji, lati ma lo afọṣẹ: o mì ọfà rẹ̀, o da òriṣa, o wo ẹ̀dọ.

### *Sise afọsẹ nipa ọpa*

Hosea 4:12

Awọn enia mi mbère ìmọ lọwọ igi wọn, ọpá wọn si nfi hàn fun wọn: nitori ẹmi agbère ti mu wọn ṣìna, nwọn si ti ṣe agbère lọ kuro labẹ Ọlọrun wọn.

### *Ijiya fun sise afọsẹ*

I Kronika 10:13, 14

Bẽni Saulu kú ninu ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o da si Oluwa, nitori ọ̀rọ Oluwa, ti on kò kiyesi, ati pẹlu nitoripe o lọ bère ọ̀ràn lọwọ abõkusọrọ, lati ṣe ibere. Kò si bère lọwọ Oluwa; nitorina li o ṣe pa a, o si yi ijọba na pada sọdọ Dafidi ọmọ Jesse.

Mika 3:7

Oju yio si tì awọn ariran, awọn alasọtẹlẹ̀ na yio si dãmu: nitõtọ, gbogbo nwọn o bò ete wọn: nitori idahùn kò si lati ọdọ Ọlọrun.

### *Awọn Keferi ntẹle awọn aworawọ*

Jeremiah 10:2

Bayi li Oluwa wi, Ẹ máṣe kọ́ ìwa awọn keferi, ki àmi ọ̀run ki o má si dãmu nyin, nitoripe nwọn ndamu awọn orilẹ-ède.

Mase Gbẹkẹle awọn iwe tabi ohunkohun fun "Oriire" ma sise jọwọ ara rẹ fun awọn orin (ilu) ẹmi esu tabi awọn aworan ti esu. "Emi ki yio gbé ohun buburu siwaju mi" —Orin Dafidi 101:3. Kọ igberaga, agabagebe, ati oku ẹsin silẹ.

Matteu 23:27, 28

Egbé ni fun nyin, ẹnyin . . . agabagebe; nitoriti ẹnyin . . . dara li ode, ṣugbọn ninu nwọn kún fun . . . ẹgbin gbogbo. Gẹgẹ bẽli ẹnyin pẹlu farahàn li ode bi olododo fun enia, ṣugbọn ninu ẹ kún fun agabagebe ati ẹ̀ṣẹ.

### *Pipa ara ẹni wa lati ọwọ esu*

Mase gba irọ Satani tabi ti awọn ẹmi esu gbọ wipe pipa ara rẹ yoo mu isoro tabi idalẹbi ọkan rẹ kuro. "Iwọ kò gbọdọ pania" —Ẹksodu 20:13.

### *Kristi nikan ni o n dani nide kuro lọwọ ẹbi*

(Wo oju ewe 48 ati 49)

Ẹksodu 15:2

OLUWA li agbara ati orin mi, on li o si di ìgbala mi: eyi li Ọlọrun mi, emi o si fi ìyin fun u; Ọlọrun baba mi, emi o gbé e leke.

### *Nipasẹ awọn wolii eke*

Jeremiah 14:14

Nigbana ni Oluwa wi fun mi pe, Awọn woli nsọ asọtẹlẹ eke li orukọ mi; emi kò rán wọn, bẽni emi kò paṣẹ fun wọn, emi kò si sọ́rọ kan fun wọn; iran eke, afọṣẹ, ati ohun asan, ati ẹ̀tan inu wọn ni awọn wọnyi sọtẹlẹ fun nyin.

Marku 13:22

Nitori awọn eke Kristi, ati awọn eke woli yio dide, nwọn o si fi àmi ati ohun iyanu hàn, tobẽ bi o ṣe iṣe, nwọn iba tàn awọn ayanfẹ pãpã.

### *Nipa biba oku sọrọ*

II Samuẹli 12:23

Nipasẹ idari Ọlọrun, Dafidi Ọba sọ nipa ti ọmọ rẹ, "Ṣugbọn nisisiyi o ti kú; . . . on ki yio si tun tọ̀ mi wá."

Mase ba awọn ẹmi esu sọrọ bikose ki o pasẹ fun wọn lati jade nipasẹ Orukọ Kristi. Mase ni igbẹkẹle ninu kika atẹlẹwọ, ọpọn ifa, igbadi, oogun dudu. "Iṣẹgun lati ọwọ Oluwa ni"—Owe 21:31b.

### *Jo gbogbo orisa ati iwe esu nina*

Iṣe 19:19, 20

Kì isi ṣe diẹ ninu awọn ti nṣe iṣẹkiṣẹ li o kó iwe wọn jọ, nwọn dáná sun wọn loju gbogbo enia: nwọn si ṣìro iye wọn, nwọn si ri i, o jẹ ẹgbãmẹdọgbọ̀n iwọn fadaka. Bẽli ọ̀rọ Oluwa si gbilẹ si i gidigidi, o si gbilẹ. (Ka Genesisi 35:2-5).

# KRISTI NI O SETO IBALO OKUNRIN ATI OBIRIN SATANI BAA JẸ

### *A da ibalo ọkunrin ati obirin fun igbeyawo nikansoso*

Genesisi 2:22 ati 24

OLUWA Ọlọrun si fi egungun-ìha ti o mu ni ìha ọkunrin na mọ obirin, o si mu u tọ̀ ọkunrin na wá. . . . Nitorina li ọkunrin yio ṣe ma fi baba on iya rẹ̀ silẹ, yio si fi ara mọ́ aya rẹ̀: nwọn o si di ara kan.

Heberu 13:4

Ki igbéyawo ki o li ọla larin gbogbo enia, ki akete si jẹ alailẽri: nitori awọn àgbere ati awọn panṣaga li Ọlọrun yio dá lẹjọ.

I Korint 7:10, 11

Ṣugbọn awọn ti o ti gbeyawo ni mo si paṣẹ fun, ṣugbọn kì iṣe emi, bikoṣe Oluwa, Ki aya máṣe fi ọkọ rẹ̀ silẹ. Ṣugbọn bi o bá si fi i silẹ, ki o wà li ailọkọ, tabi ki o ba ọkọ rẹ̀ làja: ki ọkọ ki o máṣe kọ̀ aya rẹ̀ silẹ.

(Wo Romu 7:2, Marku 10:9.)

### *Esu ni o wa lẹhin gbogbo aigbọran*

Ẹniti o ba ndẹṣẹ ti Èṣu ni; nitori lati àtetekọṣe ni Èṣu ti ndẹṣẹ.

—I Johannu 3:8a

### *Iwọ jẹ ti ẹniti o ba n gbọ tirẹ*

Ẹnyin kò mọ̀ pe, ẹniti ẹnyin ba jọwọ ara nyin lọwọ fun bi ẹrú lati mã gbọ́ tirẹ̀, ẹrú ẹniti ẹnyin ba gbọ tirẹ̀ li ẹnyin iṣe. —Romu 6:16a

Iwọ kò gbọdọ ṣe panṣaga.
—Ẹksodu 20:14

Ọkunrin ti o ba bá aya ọkunrin miran ṣe panṣaga, ani on ti o bá aya ẹnikeji rẹ̀ ṣe panṣaga, panṣaga ọkunrin ati panṣaga obirin li a o pa nitõtọ. —Lefitiku 20:10

Nitori eyi ni ifẹ Ọlọrun, ani wiwà ni mimọ́ nyin, pe ki ẹnyin ki o takéte si àgbere.
—I Tessalonika 4:3

. . . panṣaga, àgbere, . . . awọn ti nṣe nkan bawọnni kì yio jogún ijọba Ọlọrun. —Galatia 5:19b, 21b

### *Ẹsẹ si ara rẹ*

Ṣugbọn ara kì iṣe ti àgbere, bikoṣe fun Oluwa; ati Oluwa fun ara. . . . Ẹnyin kò mọ̀ pe ẹ̀ya-ara Kristi li ara nyin iṣe? . . . Ẹ mã sá fun àgbere. Gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ ti enia ndá o wà lode ara; ṣugbọn ẹniti o nṣe àgbere nṣẹ̀ si ara on tikararẹ̀.
—I Korinti 6:13b, 15a ati 18

### *Awọn obi nilati pa ọmọ wọn mọ kuro ninu ẹsẹ naa*

Máṣe bà ọmọ rẹ obirin jẹ́, lati mu u ṣe àgbere; ki ilẹ na ki o má ba di ilẹ àgbere, ati ki ilẹ na má ba kún fun iwa buburu. —Lefitiku 19:29

Pansanga: ibalopọ ọkunrin ati obirin ti ko tii gbeyawo.

Agbere: ibalopọ pẹlu ẹlomiran lẹhin ti ẹnikan ti gbeyawo.

Nitori bi gbogbo enia ti kú ninu Adamu, bẽni a ó si sọ gbogbo enia di alãye ninu Kristi. —I Korinti 15:22

Njẹ niwọn bi awọn ọmọ ti ṣe alabapin ara on ẹ̀jẹ, bẽ gẹgẹ li on pẹlu si ṣe alabapin ninu ọkanna; ki o le ti ipa ikú pa ẹniti o ni agbara ikú run, eyini ni Eṣu; Ki o si le gbà gbogbo awọn ti o ti itori ibẹru iku wà labẹ ìde lọjọ aiye wọn gbogbo.
—Heberu 2:14, 15

Nitori eyi li Ọmọ Ọlọrun ṣe farahàn, ki o le pa iṣẹ Eṣu run.
—I Johannu 3:8b

Kolosse 2:15

O si ti já awọn alaṣẹ airi ati awọn alagbara kuro li ara rẹ̀, o si ti dojuti wọn ni gbangba, o nyọ̀ ayọ̀ iṣẹgun lori wọn ninu rẹ̀.

II Tessalonika 2:8

Nigbana li a ó si fi ẹni ẹ̀ṣẹ nì hàn, ẹniti Oluwa yio fi ẽmi ẹnu rẹ̀ pa, ti yio si fi ifihan wíwa rẹ̀ sọ di asan.

### *Aiku wa fun wa ninu Kristi*

II Timoteu 1:9, 10

Ẹniti o gbà wa là, ti o si fi ìpe mimọ́ pè wa, kì iṣe gẹgẹ bi iṣe wa, ṣugbọn gẹgẹ bi ipinnu ati ore-ọfẹ tirẹ̀, ti a fifun wa ninu Kristi Jesu lati aiyeraiye, Ṣugbọn ti a fihàn nisisiyi nipa ifarahàn Jesu Kristi Olugbala wa, ẹniti o pa ikú ré, ti o si mu ìye ati aidibajẹ wá si imọlẹ nipasẹ ihinrere.

I Peteru 5:8b, 9a

. . . Èṣu, ọtá nyin, bi kiniun ti nke ramuramu, o nrìn kākiri, o nwá ẹniti yio pajẹ kiri: Ẹniti ki ẹnyin ki o kọ oju ija si pẹlu iduroṣinṣin ninu igbagbọ́ . . . .

Efesu 6:11-18a

Ẹ gbe gbogbo ihamọra Ọlọrun wọ̀, ki enyin ki o le kọ oju ija si arekereke Eṣu. Nitoripe kì iṣe ẹ̀jẹ ati ẹran-ara li awa mba jijakadi, ṣugbọn awọn alaṣẹ airi ati awọn alagbara, awọn alaṣẹ ibi òkunkun aiye yi, ati awọn ẹmí buburu ni oju ọrun. . . . ki ẹnyin ki o le duro tiri si ọjọ ibi, . . . lẹhin ti ẹ ti fi àmure otitọ di ẹgbẹ nyin, ti ẹ si ti di ìgbaiya ododo nì mọra; Ti ẹ si ti fi . . . ihinrere alafia wọ̀ ẹsẹ nyin ni bàta; Léke gbogbo rẹ̀, ẹ mu apata igbagbọ́, nipa eyiti ẹnyin ó le mã fi paná gbogbo ọfa iná ẹni ibi nì. Ki ẹ si mu aṣibori igbala, ati idà Ẹmí, ti iṣe ọ̀rọ Ọlọrun: . . . ki ẹ mã gbadura nigbagbogbo ninu Ẹmi, ki ẹ si mã ṣọra . . . .

Jakọbu 4:7

Nitorina ẹ tẹriba fun Ọlọrun. Ẹ kọ oju ija si Eṣu on ó si sá kuro lọdọ nyin.

I Johannu 4:4b

. . . (Kristi) ẹniti mbẹ ninu nyin tobi jù (Satani) ẹniti mbẹ ninu aiye lọ.

Idi ti satani fi nsa: Kristi mbẹ ninu rẹ!

### *Oun ni ohun Ọlọrun*

**Heberu 1:1a, 2**

ỌLỌRUN, ... Ni ikẹhin ọjọ wọnyi o ti ipasẹ Ọmọ rẹ ba wa sọ̀rọ, ẹniti o fi ṣe ajogun ohun gbogbo, nipasẹ ẹniti o dá awọn aiye pẹlu.

**Marku 1:22**

Ẹnu si yà wọn si ẹkọ́ rẹ: nitoriti o nkọ́ wọn bi ẹniti o li aṣẹ, kì isi ṣe bí awọn akọwe.

**Matteu 7:29**

Nitori o nkọ́ wọn bi ẹniti o li aṣẹ, ki si iṣe bi awọn akọwe.

**I Kọrinti 8:6**

Ṣugbọn fun awa Ọlọrun kan ni mbẹ, Baba, lọwọ ẹniti ohun gbogbo ti wá, ati ti ẹniti gbogbo wa iṣe; ati Oluwa kanṣoṣo Jesu Kristi, nipasẹ ẹniti ohun gbogbo wà, ati awa nipasẹ rẹ.

**Johannu 5:27**

O si fun u li aṣẹ lati mã ṣe idajọ pẹlu, nitoriti on iṣe Ọmọ-enia.

**I Peteru 3:22**

Ẹniti o ti lọ si ọrun, ti o si mbẹ li ọwọ́ ọtún Ọlọrun; ori awọn angẹli, ati awọn ọlọlá, ati awọn alagbara si ntẹriba fun.

**Romu 14:9**

Nitori idi eyi na ni Kristi ṣe kú, ti o si tún yè, ki o le jẹ Oluwa ati okú ati alãye.

**Matteu 28:18**

Jesu si wá, o si sọ fun wọn, wipe, Gbogbo agbara li ọrun ati li aiye li a fifun mi.

Marku 4:39

O si ji, o ba afẹfẹ, na wi, o si wi fun okun pe, Dakẹ jẹ. Afẹfẹ si da, iparọrọ nla si de.

### *O wosan pẹlu asẹ*

Marku 2:10-12a

Ṣugbọn ki ẹ le mọ̀ pe, Ọmọ-enia li agbara li aiye lati dari ẹ̀ṣẹ jìni, (o wi fun ẹlẹgba na pe,) Mo wi fun ọ, Dide, gbé akete rẹ, ki o si mã lọ ile rẹ. O si dide lojukanna, o si gbé akete na, o si jade lọ li oju gbogbo wọn; tobẹ̃ ti ẹnu fi yà gbogbo wọn, nwọn si yìn Ọlọrun logo.

Marku 1:31

O si wá, o fà a lọwọ, o si gbé e dide; lojukanna ibà na si fi i silẹ, o si nṣe iranṣẹ fun wọn.

### *Kristi n le Ẹmi Esu jade*

Marku 1:26, 27

Nigbati ẹmi aimọ́ na si gbé e ṣanlẹ, o ke li ohùn rara, o si jade kuro lara rẹ̀. Hà si ṣe gbogbo wọn, tobẹ̃ ti nwọn fi mbi ara wọn lẽre, wipe, Kili eyi? ẹkọ́ titun li eyi? nitoriti o fi agbara paṣẹ fun awọn ẹmi aimọ́, nwọn si gbọ́ tirẹ̀.

### *O ji awọn oku pẹlu asẹ*

Luku 7:14b, 15

O si wipe, Ọdọmọkunrin, mo wi fun ọ, Dide. Ẹniti o kú na si dide joko, o bẹ̀rẹ si ohùn ifọ̀. O si fà a le iya rẹ̀ lọwọ.

# KRISTI FUN AWỌN OLUTẸLE RẸ NI ASẸ ATI AGBARA LORI GBOGBO AGBARA ỌTA

## Luku 10:19
Kiyesi i, emi fun nyin li aṣẹ lati tẹ ejò ati akẽkẽ mọlẹ, ati lori gbogbo agbara ọtá: kò si si ohunkan bi o ti wù ki o ṣe, ti yio pa-nyin-lara.

## Luku 9:1
O si pè awọn ọmọ-ẹhin rẹ mejila jọ, o si fun wọn li agbara on aṣẹ lori awọn ẹmi èṣu gbogbo, ati lati wò arùn sàn.

## Marku 11:23
Lõtọ ni mo wi fun nyin, Ẹnikẹni ti o ba wi fun òke yi pe, Ṣidi, ki o si bọ sinu okun; ti kò ba si ṣiyemeji li ọkàn rẹ, ṣugbọn ti o ba gbagbọ pe ohun ti on wi yio ṣẹ, yio ri bẹ̃ fun u.

## Johannu 14:12a
Lõtọ, lõtọ ni mo wi fun nyin, Ẹniti o ba gbà mi gbọ́, iṣẹ ti emi nṣe li on na yio ṣe pẹlu.

## Filippi 4:13
Emi le ṣe ohun gbogbo ninu Kristi ẹniti nfi agbara fun mi.

## Marku 9:23
Jesu si wi fun u pe, Bi iwọ ba le gbagbọ́, ohun gbogbo ni ṣiṣe fun ẹniti o ba gbagbọ́.

## Efesu 1:19
Ati agbara rẹ ti o tobi julọ si awa ti o gbagbọ́, gẹgẹ bi iṣẹ agbara rẹ.

### *Ba wọn wi, ki o si fi asẹ le wọn jade ni orukọ Jesu*

**Marku 5:8, 9 ati 13b**

**Nitoriti o wi fun u pe, Jade kuro lara ọkunrin na, iwọ ẹmi aimọ́. O si bi i lẽre pe, Orukọ rẹ? O si dahùn, wipe, Legioni li orukọ mi: nitori awa pọ̀. . . . Awọn emi aimọ́ si jade, nwọn si wọ̀ inu awọn ẹlẹdẹ lọ . . . .**

**Marku 9:25-27 ati 29**

**Nigbati Jesu si ri pe ijọ enia nsare wọjọ pọ̀, o ba ẹmi aimọ́ na wi, o wi fun u pe, Iwọ odi ati aditi ẹmi, mo paṣẹ fun ọ, jade lara rẹ̀, ki iwọ má ṣe wọ̀ inu rẹ̀ mọ̀. On si kigbe soke, o si nà a tàntàn, o si jade lara rẹ̀: ọmọ na si dabi eniti o kú; tobẹ ti ọpọlọpọ fi wipe, O kú. Ṣugbọn Jesu mu u li ọwọ́, o si fà a soke; on si dide. . . . O si wi fun wọn pe, Irú yi kò le ti ipa ohun kan jade, bikoṣe nipa adura ati àwẹ.**

**Iṣe 16:18b**

**Paulu . . . si yipada, o wi fun emí na pe, Mo paṣẹ fun ọ li orukọ Jesu Kristi ki o jade kuro lara rẹ̀. O si jade ni wakati kanna.**

**Luku 4:35**

**Jesu si ba a wi, o ni, Pa ẹnu rẹ mọ́, ki o si jade lara rẹ̀. Nigbati ẹmi eṣu na si gbé e ṣanlẹ li awujọ, o jade kuro lara rẹ̀, kò si pa a lara.**

Filipi 2:9, 10a

Nitorina Ọlọrun pẹlu si ti gbé e ga gidigidi, o si ti fi orukọ kan fun u ti o bori gbogbo orukọ: Pe, li orukọ Jesu ni ki gbogbo ẽkun ki o mã kunlẹ.

Johannu 14:13

Ohunkohun ti ẹnyin ba si bère li orukọ mi, on na li emi ó ṣe, ki a le yin Baba logo ninu Ọmọ.

Lẹhin igbati mo mu iyawo mi ati idile mi nipa igbagbọ pada si ilẹ Afrika lati sisẹ fun Kristi, mo taji ni oru ọjọ kan pẹlu ẹmi esu kan ti o sun le mi lori. Nigbati mo fi eekun mi gbun tirẹ wo, ki nlee mọ boya otitọ ni, o ti eekun mi pada lẹsẹkannaa pẹlu agbara nla, ni kiamọsa o ti sun mọ ibi ọrun mi lati fun mi pa. Mo ni akoko lati sọ ọrọ mẹrin pere, "Jesu, ran mi lọwọ!" Lẹsẹkannaa, o ti lọ, nko si tun ti pada ni iru iriri bẹẹ lati ọdun mejidinlọgbọn yi wa. Agbara nla ti o bani lẹru mbẹ ninu Orukọ Jesu Kristi lori Esu ati gbogbo ẹmi esu! Kepe orukọ Kristi fun igbala ati idande (Romu 10:13).

Obirin kan sọ fun iyawo mi ati emi wipe nigbati oun wa ni ile-iwe giga, ọdọmọkunrin kan mu oun rin lọ ni oju ọna irin. Ni ibikan, o gbiyanju lati paa, ki o si se bi ẹnipe ọkọ oju-irin ni o paa. Nigbati Obirin naa pasẹ fun ọmọkunrin naa ni orukọ Jesu Kristi, ko ni agbara lori rẹ mọ. Ninu agba-

ra Jesu, o mu ki ọmọkunrin naa rin niso niwaju rẹ titi ti wọn fi pada de ile-iwe.

Obirin miran ẹwẹ tun sọ fun iyawo mi ati emi wipe nigbati oun wa ni ọdọ, nipa aimọkan oun pe awọn alafọsẹ wa si ile oun. Lẹhin igbanaa, ni gbogbo igba ni awọn ẹmi esu maa nwa lati da awọn nkan ru ninu ile naa. Ni ibẹru bojo o le wọn jade ni orukọ Jesu. Laipẹ, o jọwọ ara rẹ patapata fun Jesu Kristi.

Mase kaanu ṭabi se oju aanu si Esu tabi awọn ẹmi esu. Ete wọn ni wipe ki o fara mọ awọn ju wipe ki o fara mọ Ọlọrun. Kristiani alagba kan ti o se aisan ti o si ni arun ọpọlọ sọ fun mi awọn ohun ti satani nsọ fun un. O sọ wipe oun n ronu "lati gba satani laaye wo." Mo sọ fun wipe ọga ni Satani nipa titan eniyan ati wipe eniyan ko lee gbẹkẹ le ọrọ kansoso ti satani ba sọ. Mo ba esu wi ni orukọ nla julọ ti Jesu Kristi. Ọkunrin naa wipe "Mo layọ pe o wa lalẹ oni." O si ni ibalẹ ọkan fun ọsẹ bii marun ti o se ki o to ku.

—Watson Goodman

### *Kristi ni Ọlọrun Ẹlẹda*

Kolosse 1:16

Nitori ninu rẹ li a ti dá ohun gbogbo, ohun ti mbẹ li ọrun, ati ohun ti mbẹ li aiye, eyiti a ri, ati eyiti a kò ri, nwọn iba ṣe itẹ, tabi oye, tabi ijọba, tabi ọla: nipaṣẹ rẹ li a ti dá ohun gbogbo, ati fun u.

### *Kristi n fun ni ni Imọlẹ ati Alafia*

Luku 1:79

Lati fi imọlẹ fun awọn ti o joko li òkunkun ati li ojiji ikú, ati lati fi ẹsẹ wa le ọna alafia.

II Tessalonika 3:16a

Njẹ ki Oluwa alafia tikararẹ mã fun nyin ni alafia nigbagbogbo.

### *Ẹmi Esu ati Satani n panirun*

Johannu 10:10a

Olè kì iwá bikoṣe lati jale, ati lati pa, ati lati parun.

Ifihàn 12:12b

Egbé ni fun aiye . . . nitori Èṣu sọkalẹ tọ̀ nyin wá ni ibinu nla, nitori o mọ̀ pe ìgba kukuru ṣá li on ni.

### *Satani n fun ni Okunkun ati idaloro*

Owe 4:19

Ọna awọn enia buburu dabi òkunkun: Nwọn kò mọ̀ ohun ti nwọn ndugbolu.

Luku 16:22b, 23a

Ọlọ̀rọ̀ na si kú pẹlu, a si sin i; Ni ipo-oku li o gbé oju rẹ soke, o mbẹ ninu iṣẹ oró.

### *Kristi ni Otitọ*

Johannu 1:14 ati 8:31b, 32

Ọ̀rọ na si di ara, on si mba wa gbé, (awa si nwò ogo rẹ̀, ogo bi ti ọmọ bíbi kanṣoṣo lati ọdọ Baba wá,) o kún fun ore-ọfẹ ati otitọ. . . . Bi ẹnyin ba duro ninu ọ̀rọ mi, nigbana li ẹnyin jẹ ọmọ-ẹhin mi nitõtọ. Ẹ ó si mọ̀ otitọ, otitọ yio si sọ nyin di omnira.

### *Kristi kun fun Ifẹ*

I Johannu 3:16

Nipa eyi li awa mọ̀ ifẹ, nitoriti o fi ẹmi rẹ̀ lelẹ fun wa: o si yẹ ki awa fi ẹmí wa lelẹ fun awọn ará.

I Johannu 4:19

Awa fẹran rẹ̀ nitori on li o kọ́ fẹran wa.

### *Satani ni Baba irọ*

Johannu 8:44

Ti eṣu baba nyin li ẹnyin iṣe, ifẹkufẹ baba nyin li ẹ si nfẹ ṣe. Apania li on iṣe lati atetekọṣe, ko si duro ni-otitọ; nitoriti kò si otitọ ninu rẹ̀. Nigbati o ba nṣeke, ninu ohun tirẹ̀ li o nsọ, nitori eke ni, ati baba eke.

### *Satani n fa ikorira*

Johannu 15:18

Bi aiye ba korira nyin, ẹ mọ̀ pe, o ti korira mi ṣaju nyin.

Galatia 5:19a, 20

Njẹ awọn iṣẹ ti ara farahàn, . . . irira, . . . ibinu.

### *Kristi n wẹ inu ọkan mọ*

I Johannu 1:7

Ṣugbọn bi awa ba nrìn ninu imọlẹ, bi on ti mbẹ ninu imọlẹ, awa ní ìdapọ pẹlu ara wa, ẹ̀jẹ Jesu Kristi Ọmọ rẹ̀ ni nwẹ̀ wa nù kuro ninu ẹṣẹ gbogbo.

### *Kristi n dani nide kuro lọwọ ẹṣẹ*

Romu 5:9

Melomelo si ni, ti a da wa lare nisisiyi nipa ẹ̀jẹ rẹ̀, li a o gbà wa là kuro ninu ibinu nipasẹ rẹ̀.

### *Kristi n fun ni ni iye ainipẹkun*

Johannu 17:3

Iye ainipẹkun na si li eyi, ki nwọn ki o le mọ̀ ọ, iwọ nikan Ọlọrun otitọ, ati Jesu Kristi, ẹniti iwọ rán.

### *Satani maa n ba ọkan jẹ*

Galatia 6:7, 8a

Ki a máṣe tàn nyin jẹ; a kò le gàn Ọlọrun: nitori ohunkohun ti enia ba funrugbin, on ni yio si ká. Nitori ẹniti o ba nfunrugbin sipa ti ara rẹ̀, nipa ti ara ni yio ká idibaje.

### *Satani maa n ti eniyan sinu ẹṣẹ*

I Johannu 3:8b

Ẹniti o ba ndẹṣẹ ti Èṣu ni; nitori lati àtetekọṣe ni Èṣu ti ndẹṣẹ.

### *Satani n mu ni lọ sinu iku ayeraye*

Matteu 13:38b-40a

. . . èpo si li awọn ọmọ ẹni-buburu ni; Ọta ti o fún wọn li Èṣu; . . . a ti kó èpo jọ, . . . a si fi iná sun wọn.

***Oun ni ise ọmọ alade aye yi nisiyi***

Johannu 14:30

Emi (Jesu) ki o ba nyin sọ̀rọ pipọ: nitori alade aiye yi wá, kò si ni nkankan lọdọ mi.

***Satani ni ọmọ-alade. Bi awọn nkan ko ba lọ deede, d'ẹbi fun un***

Jakọbu 3:15, 16

Ọgbọ́n yi ki iṣe eyiti o ti oke sọkalẹ wá, ṣugbọn ti aiye ni, ti ara ni, ti ẹmí èṣu ni. Nitori ibiti owú on ìja bá gbé wà, nibẹ̀ ni rudurudu ati iṣẹ buburu gbogbo wà.

***Nigbati Satani ba ri aye, o maa mba ominira lati sin Kristi ni gbangba jẹ. Ko le ba ifẹ-ọkan rẹ fun Kristi jẹ.***

***Pa igbagbọ mọ!***

***Se olootọ si Kristi de oju iku***

Iṣe 7:59, 60

Nwọn sọ Stefanu li okuta, o si nképe Oluwa wipe, Jesu Oluwa, gbà ẹmí mi. O si kunlẹ, o kigbe li ohùn rara pe, Oluwa, má kà ẹ̀ṣẹ yi si wọn li ọrùn. Nigbati o si wi eyi, o sùn.

***Ijọba agbaye Kristi***

Isaiah 9:7a

Ijọba yio bi si i, alafia ki yio ni ipẹkun, lori itẹ Dafidi, ati lori ijọba rẹ̀, lati ma tọ́ ọ, ati lati fi idi rẹ̀ mulẹ, nipa ẹtọ ati ododo lati isisiyi lọ, ani titi lai.

*Ẹni—ẹsẹ gba agbara lọwọ Satani*

II Tessalonika 2:1, 3, 4, 8-9

Ṣugbọn awa mbẹ̀ nyin, ará, nitori ti wíwa Jesu Kristi Oluwa wa, ati ti ipejọ wa sọdọ rẹ̀, . . . Ẹ máṣe jẹ ki ẹnikẹni tàn nyin jẹ lọnakọna; nitoripe ọjọ na ki yio de, bikoṣepe ìyapa nì ba kọ́ de, ki a si fi ẹni ẹ̀ṣẹ nì hàn, ti iṣe ọmọ ègbé; ẹniti nṣòdì, ti o si ngbé ara rẹ̀ ga si gbogbo ohun ti a npè li Ọlọrun, tabi ti a nsin; tobẹ ti o joko ni tẹmpili Ọlọrun, ti o nfi ara rẹ̀ hàn pe Ọlọrun li on. . . . Nigbana li a ó si fi ẹni ẹ̀ṣẹ nì hàn, ẹniti Oluwa yio fi ẽmi ẹnu rẹ̀ pa, ti yio si fi ifihan wíwa rẹ̀ sọ di asan: Ani on, ẹniti wíwa rẹ̀ yio ri gẹgẹ bi iṣẹ Satani pẹlu agbara gbogbo, ati àmi ati iṣẹ-iyanu eke.

Ifihàn 13:2b ati 6, 7b

. . . ikõko (Satani) na si fun u li agbara rẹ̀, ati itẹ rẹ̀, ati ọlá nla. . . . O si yà ẹnu rẹ̀ ni ọrọ-odi si Ọlọrun, lati sọ ọrọ-odi si orukọ rẹ̀, ati si agọ́ rẹ̀, ati si awọn ti ngbe ọrun. . . . a si fi agbara fun u lori gbogbo ẹya, ati enia, ati ède, ati orilẹ.

Ifihàn 13:4

Nwọn si foribalẹ fun ikõko na nitori o ti fun ẹranko na ni ọla: nwọn si foribalẹ fun ẹranko na, wipe, Tali o dabi ẹranko yi? tali o si le ba a jagun?

Danieli 7:25, 26

On o si ma sọ̀rọ nla si Ọga-ogo, yio si da awọn enia-mimọ́ ti Ọga-ogo lagara, yio si rò lati yi akokò ati ofin pada; a o si fi wọn le e lọwọ titi fi di igba akokò kan, ati awọn akokò, ati idaji akokò. Ṣugbọn awọn onidajọ yio joko, nwọn o si gbà agbara ijọba rẹ̀ lọwọ rẹ̀ lati fi ṣòfo, ati lati pa a run de opin.

Ifihàn 13:5-9

A si fun u li ẹnu lati mã sọ ohun nla ati ọrọ-odi; a si fi agbara fun u lati ṣe bẹ ẹ ni oṣu mejilelogoji. O si yà ẹnu rẹ̀ ni ọrọ-odi si Ọlọrun, lati sọ ọrọ-odi si orukọ rẹ̀, ati si agọ́ rẹ̀, ati si awọn ti ngbe ọrun. A si fi fun u lati mã ba awọn enia mimọ́ jagun, ati lati ṣẹgun wọn: a si fi agbara fun u lori gbogbo ẹya, ati enia, ati ède, ati orilẹ. Gbogbo awọn ti ngbe ori ilẹ aiye yio si mã sin i, olukuluku ẹniti a kò kọ orukọ rẹ̀ sinu iwe iyè Ọdọ-Agutan ti a ti pa lati ipilẹṣẹ aiye. Bi ẹnikẹni ba li etí ki o gbọ́.

I Timoteu 6:12

Mã jà ìja rere ti igbagbọ́, di ìye ainipẹkun mu ninu eyiti a gbé pè ọ si, ti iwọ si ṣe ijẹwọ rere niwaju ẹlẹri pupọ̀.

### *Awọn olori ẹlẹsin aye ran Asodisi Kristi lọwọ lati tan aye jẹ. Sin tabi ki o ku!*

Ifihàn 13:14-17 ati 19:20

O si ntàn awọn ti ngbe ori ilẹ aiye jẹ nipa awọn ohun iyanu ti a fi fun u lati ṣe niwaju ẹranko na; o nwi fun awọn ti ngbe ori ilẹ aiye lati ya aworan fun ẹranko na ti o ti gbà ọgbẹ idà, ti o si yè. A si fi fun u lati fi ẹmí fun aworan ẹranko na ki o mã sọ̀rọ, ki o si mu ki a pa gbogbo awọn ti kò foribalẹ fun aworan ẹranko na. O si mu gbogbo wọn, ati kekere ati nla, ọlọ̀rọ ati talakà, omnira ati ẹrú, ki a fi àmi kan fun wọn li ọwọ́ otún wọn, tabi ni iwaju wọn: Ati ki ẹnikẹni má le rà tabi ki o tà, bikoṣe ẹniti o bá ni ami orukọ ẹranko na, tabi iye orukọ rẹ̀. . . . A si mu ẹranko na, ati woli eke nì pẹlu rẹ̀, ti o ti nṣe iṣẹ iyanu niwaju rẹ̀, eyiti o ti fi ntàn awọn ti o gbà àmi ẹranko na ati awọn ti nforibalẹ fun aworan rẹ̀ jẹ. Awọn mejeji yi li a sọ lãye sinu adagun iná.

### *Awọn eniyan Ọlọrun kọ awọn ọlọrun miran*

Bi o ba ri bẹ̃, Ọlọrun wa, ti awa nsìn, le gbà wa lọwọ iná ileru na ti njo, on o si gbà wa lọwọ rẹ, ọba. Ṣugbọn bi bẹ̃kọ, ki o ye ọ, ọba, pe, awa kì yio sìn oriṣa rẹ, bẹ̃li awa kì yio si tẹriba fun ere wura ti iwọ gbé kalẹ. —Danieli 3:17, 18

Ifihàn 13:16-18

O si mu gbogbo wọn, ati kekere ati nla, ọlọrọ̀ ati talakà, omnira ati ẹrú, ki a fi àmi kan fun wọn li ọwọ́ ọtún wọn, tabi ni iwaju wọn: Ati ki ẹnikẹni má le rà tabi ki o tà, bikoṣe ẹniti o bá ni ami orukọ ẹranko na, tabi iye orukọ rẹ̀. Nihin ni ọgbọ́n gbé wà. Ẹniti o ba ni oye, ki o ṣiro iye ti mbẹ lara ẹranko na: nitori iye enia ni; iye rẹ̀ na si jẹ ọ̀talelẹgbẹta o le mẹfa (666).

***Ọjọ daradara mbọ fun awọn ti a ti gbala***

Ifihàn 7:14b-17

. . . Awọn wọnyi li o jade lati inu ipọnju nla, nwọn si fọ̀ aṣọ wọn, nwọn si sọ wọn di funfun ninu ẹ̀jẹ Ọdọ-Agutan na. Nitorina ni nwọn ṣe mbẹ niwaju itẹ́ Ọlọrun, ti nwọn si nsin i li ọsán ati li oru ninu tẹmpili rẹ̀: Ẹniti o joko lori itẹ́ na yio si ṣiji bò wọn. Ebi kì yio pa wọn mọ́, bẽli ongbẹ kì yio gbẹ wọn mọ́; Bẽli õrùn kì yio pa wọn tabi õrukõru. Nitori Ọdọ-Agutan ti mbẹ li arin itẹ́ na ni yio mã ṣe oluṣọ-agutan wọn, ti yio si mã ṣe amọna wọn si ibi orisun omi iyè: Ọlọrun yio si nù omije gbogbo nù kuro li oju wọn.

**O dara julọ lati wọ Ọrun rere pẹlu ebi ju ati lọ si ọrun apaadi pẹlu ayo!**

# IPARUN FUN GBOGBO ẸNITI O BA SIN ASODISI KRISTI, TABI TI O BA GBA AMI RẸ SI ARA WỌN KII WỌN BA LEE TA TABI RA

Ifihàn 14:7, 9-13

O nwi li ohùn rara pe, Ẹ bẹru Ọlọrun, ki ẹ si fi ogo fun u; nitoriti wakati idajọ rẹ de: ẹ si foribalẹ fun ẹniti o dá ọrun, on aiye, ati okun, ati awọn orisun omi.

Angẹli miran ẹkẹta si tẹle wọn, o nwi li ohùn rara pe, Bi ẹnikẹni ba nforibalẹ fun ẹranko nì, ati aworan rẹ, ti o si gbà àmi si iwaju rẹ tabi si ọwọ rẹ.

On pẹlu yio mu ninu ọti-waini ibinu Ọlọrun, ti a tú jade li aini àbula sinu ago irunu rẹ; a o si fi iná ati imi-ọjọ da a loró niwaju awọn angẹli mimọ, ati niwaju Ọdọ-Agutan:

Ẹfin oró wọn si nlọ soke titi lailai, nwọn kò si ni isimi li ọsán ati li oru, awọn ti nforibalẹ fun ẹranko na ati fun aworan rẹ, ati ẹnikẹni ti o ba si gbà àmi orukọ rẹ.

Nihin ni sũru awọn enia mimọ gbé wà: awọn ti npa ofin Ọlọrun ati igbagbọ Jesu mọ.

Mo si gbọ ohùn kan lati ọrun wá nwi fun mi pe, Kọwe rẹ, Alabukún fun li awọn okú ti o kú nipa ti Oluwa lati ìhin lọ: Bẹni, li Ẹmí wi, ki nwọn ki o le simi kuro ninu lãlã wọn, nitori iṣẹ wọn ntọ wọn lẹhin.

# ISẸGUN LORI AMI ATI ERE SATANI SAAJU KI 37 IBINU ỌLỌRUN TO WA SI ILE AYE

### Ifihàn 15:1b-3 ati 16:1

Awọn angẹli meje ti o ni awọn arun meje ikẹhin, nitori ninu wọn ni ibinu Ọlọrun de opin. Mo si ri bi ẹnipe òkun digí ti o dàpọ pẹlu iná: awọn ti o si duro lori okun digi yi jẹ awọn ti nwọn ti ṣẹgun ẹranko na, ati aworan rẹ̀, ati ami rẹ̀ ati iye orukọ rẹ̀, nwọn ni harpu Ọlọrun. Nwọn si nkọ orin ti Mose, iranṣẹ Ọlọrun, ati orin ti Ọdọ Agutan, wipe, Titobi ati iyanu ni awọn iṣẹ rẹ Oluwa Ọlọrun Olodumare; Ododo ati otitọ li ọ̀na rẹ, Iwọ Ọba awọn orilẹ-ede. . . . Mo si gbọ́ ohùn nla kan lati inu tẹmpili wá, nwi fun awọn angẹli meje nì pe, Ẹ lọ, ẹ si tú ìgo ibinu Ọlọrun wọnni si ori ilẹ aiye. *(Ifihan 16-18: Ajakalẹ arun meje ati ayọrisi rẹ.)*

### *Awọn ajẹriku jọba*

### Ifihàn 20:4

Mo si ri awọn ìte, nwọn si joko lori wọn, a si fi idajọ fun wọn: mo si ri ọkàn awọn ti a ti bẹ́ lori nitori ẹrí Jesu, ati nitori ọ̀rọ Ọlọrun, ati awọn ti kò si foribalẹ fun ẹranko na, ati fun aworan rẹ̀, tabi ti kò si gbà àmi rẹ̀ ni iwaju wọn ati li ọwọ́ wọn; nwọn si wà lãye, nwọn si jọba pẹlu Kristi li ẹgbẹrun ọdún.

### *Awọn ẹmi esu ko awọn orile-ede jọ lati ja*

Nitori ẹmi èṣu ni wọn, ti nṣe iṣẹ-iyanu, awọn ti njade lọ sọdọ awọn ọba gbogbo ilẹ aiye, lati gbá wọn jọ sì ogun ọjọ nla Ọlọrun Olodumare. . . . O si gbá wọn jọ si ibikan ti a npè ni Har-mageddoni li ède Heberu. —Ifihàn 16:14 ati 16

### *Kristi da ilẹ Rẹ ati awọn eniyan ayanfẹ Rẹ, Israeli nide*

Sekariah 12:2a, 3; 14:3, 4 ati 12

Kiyesi i emi o sọ Jerusalemu di ago iwarìri . . . Li ọjọ na li emi o sọ Jerusalemu di ẹru okuta fun gbogbo enia: gbogbo awọn ti o ba si fi dẹrù pa ara wọn li a o ke si wẹwẹ, bi gbogbo awọn orilẹ-ède aiye tilẹ ko ara wọn jọ si i. . . .

Nigbana ni Oluwa yio jade lọ, yio si ba awọn orilẹ-ède wọnni jà, gẹgẹ bi iti ijà li ọjọ ogun. Ẹsẹ rẹ yio si duro li ọjọ na lori oke Olifi, ti o wà niwaju Jerusalemu ni ila-õrùn, oke Olifi yio si là meji si ihà ila-õrun ati si ihà ìwọ-õrùn, afonifojì nlanla yio wà: idajì oke na yio si ṣi sihà ariwa, ati idajì rẹ siha gusu. . . . Eyi ni yio si jẹ àrun ti Oluwa yio fi kọlu gbogbo awọn enia ti o ti ba Jerusalemu ja; ẹran-ara wọn yio rù nigbati nwọn duro li ẹsẹ̀ wọn, oju wọn yio si rà ni ihò wọn, ahọn wọn yio si sọkì li ẹnu wọn.

Bi Ọlọrun bá wà fun wa, tani yio kọ oju ija si wa? —Romu 8:31b

Romu 1:18

Nitori a fi ibinu Ọlọrun hàn lati ọrun wá si gbogbo aiwa-bi-Ọlọrun ati aiṣododo enia, awọn ẹniti o fi aiṣododo tẹ otitọ mọ́lẹ̀.

Ifihàn 19:15, 16

Ati lati ẹnu rẹ̀ ni idà mimu ti njade lọ, ki o le mã fi iṣá awọn orilẹ-ède: on o si mã fi ọpá irin ṣe akoso wọn: o si ntẹ ifúnti irunu ati ibinu Ọlọrun Olodumare. O si ni lara aṣọ rẹ̀ ati ni itan rẹ̀ orukọ kan ti a kọ: ỌBA AWỌN ỌBA, ATI OLUWA AWỌN OLUWA.

***Asodisi Kristi yoo jọba fun igba diẹ. Kristi yoo jọba nihin fun ẹgbẹrun ọdun, lẹhin naa yoo maa jọba titi lae.***

Ifihàn 20:6b

Ṣugbọn nwọn o jẹ alufa Ọlọrun ati ti Kristi, nwọn o si mã jọba pẹlu rẹ̀ li ẹgbẹ̀run ọdún.

Danieli 2:44a

Li ọjọ awọn ọba wọnyi li Ọlọrun ọrun yio gbe ijọba kan kalẹ, eyi ti a kì yio le parun titi lai.

***Gbogbo orile ede lati sin Kristi OLUWA***

Orin Dafidi 86:9

Gbogbo awọn orilẹ-ède ti iwọ da ni yio wá, nwọn o si sìn niwaju rẹ, Oluwa; Nwọn o si ma fi ogo fun orukọ rẹ.

Ifihàn 12:7-10

Ogun si mbẹ li ọrun: Mikaeli ati awọn angẹli rẹ ba ikõko na jàgun; ìkõko si jàgun ati awọn angẹli rẹ. Nwọn kò si le ṣẹgun; bẽni a kò si ri ipo wọn mọ́ li ọrun. A si lé ikõko nla na jade, ejò lailai nì, ti a npè ni Èṣu, ati Satani, ti ntàn gbogbo aiye jẹ: a si lé e jù si ilẹ aiye, a si le awọn angẹli rẹ jade pẹlu rẹ. Mo si gbọ́ ohùn rara li ọrun, nwipe, Nigbayi ni igbala de, ati agbara, ati ijọba Ọlọrun wa, ati ọla ti Kristi rẹ̀; nitori a ti lé olufisùn awọn arakunrin wa jade, ti o nfi wọn sùn niwaju Ọlọrun wa lọsán ati loru.

***Awọn ohun ija iṣẹgun ninu ogun yii***

Ifihàn 12:11

Nwọn si ṣẹgun rẹ̀ nitori ẹ̀jẹ Ọdọ Agutan na, ati nitori ọ̀rọ ẹrí wọn, nwọn kò si fẹran ẹmi wọn ani titi de iku.

***Atubọtan Satani ayeraye***

Ifihàn 20:9 ati 10

Nwọn si gòke lọ la ibú aiye ja, nwọn si yi ibudo awọn enia mimọ́ ká ati ilu ayanfẹ na: iná si ti ọrun sọkalẹ wá, o si jo wọn run. A si wọ́ Èṣu ti o tàn wọn jẹ lọ sinu adagun iná ati imi-ọjọ, nibiti ẹranko ati woli eke nì gbé wà, a o si mã dá wọn loro t'ọsan-t'oru lai ati lailai.

Lusiferi iba ti se igbọran ninu ayọ ọrun ayeraye, ṣugbọn o gbidanwo lati se alakoso Ijọba Ọlọrun.

*(Ka Isaiah 14:13, 14 ni oju ewe 3.)*

### *Kristi Oluwa jọba laelae*

I Kronika 29:11

Tirẹ, Oluwa, ni titobi, ati agbara, ati ogo, ati iṣẹgun, ati ọlá-nla: nitori ohun gbogbo li ọrun ati li aiye tirẹ ni; ijọba ni tirẹ, Oluwa, a si gbé ọ leke li ori fun ohun gbogbo.

I Korint 15:22-26

Nitori bi gbogbo enia ti kú ninu Adamu, bẽni a ó si sọ gbogbo enia di alãye ninu Kristi. Ṣugbọn olukuluku enia ni ipa tirẹ: Kristi akọbi; lẹhin eyini awọn ti iṣe ti Kristi ni bibọ rẹ. Nigbana ni opin yio de, nigbati o ba ti fi ijọba fun Ọlọrun ani Baba; nigbati o ba ti mu gbogbo aṣẹ ati gbogbo ọla ati agbara kuro. Nitoripe on kò le ṣaima jọba titi yio fi fi gbogbo awọn ọta sabẹ ẹsẹ rẹ. Ikú ni ọtá ikẹhin ti a ó parun.

Ifihàn 11:15

Angẹli keje si fun ipè; a si gbọ́ ohùn nla lat ọrun wá, wipe, Ijọba aiye di ti Oluwa wa, ati ti Kristi rẹ; on o si jọba lai ati lailai.

Matteu 18:3

O si wipe, Lõtọ ni mo wi fun nyin, bikoṣepe ẹnyin ba pada, ki ẹ si dabi awọn ọmọ kekere, ẹnyin kì yio le wọle ijọba ọrun.

# SATANI ATI AWỌN ẸMI ESU, AWỌN ỌTA RẸ

***Satani nba ara ati ọkan jẹ nipa ibalo ti ko tọ, pipa awọn ọmọ ti a ko ti bi, ifi ara ẹni fun ẹmi esu***

Romu 1:27

Gẹgẹ bẽ li awọn okunrin pẹlu, nwọn a mã fi ilò obirin nipa ti ẹda silẹ, nwọn a mã ni ifẹkufẹ gbigbona si ara wọn; ọkunrin mba ọkunrin ṣe eyi ti kò yẹ, nwọn si njẹ ère ìṣina wọn ninu ara wọn bi o ti yẹ si.

Owe 6:16, 17

Ohun wọnyi . . . li Oluwa korira: . . . ọwọ ti nta èjẹ alaiṣẹ silẹ.

Matteu 12:45a

Nigbana li o lọ, o si mu ẹmi meje miran pẹlu ara rè̩, ti o buru jù on tikararè̩ lọ; nwọn bọ si inu rè̩, nwọn si ngbé ibè̩; igbẹhin ọkunrin na si buru jù iṣaju rè̩ lọ.

Maa wa Ọlọrun Alaaye nikansoso. Mase kepe ọlọrun miran lati mọ ọjọ iwaju, lati mọ ọkan ẹlomiran, lati ni iwosan tabi fun itọni ti ẹmi.

Satani, ọlọtẹ si Ọlọrun, wa lẹhin gbogbo nkan wọnyi O n sisẹ nipasẹ awọn eniyan, iwe, awọn nkan ti a lee fojuri, ati ẹsin eke. Ohun ti o ba se lee dabi isẹ iyanu ati ohun ti o rannilwọwọ ni akọkọ, ṣugbọn o n mu eniyan wa si abẹ ide buburu satani. Kristi nikansoso ni o lee tu ọ silẹ.

Mase jọwọ ara rẹ fun ẹmikẹmi miran ti kii se ti Ẹmi Mimọ Ọlọrun. Gba Bibeli ati Oluwa Jesu Kristi nikansoso gbọ.

***(Wo Ifihàn 19:13).***

### *Ẹkọkẹkọ ti o ba ti dari eniyan kuro ni ọna tooro ti Idariji, Iwe mimọ ati Irapada Nipasẹ Ẹjẹ ati Ara Kristi jẹ eke ati ẹtan*

Matteu 24:4, 5 ati 11

Jesu si dahùn, o si wi fun wọn pe, Ẹ kiyesara, ki ẹnikẹni ki o máṣe tàn nyin jẹ. Nitori ọpọlọpọ yio wá li orukọ mi, wipe, Emi ni Kristi; nwọn ó si tàn ọ̀pọlọpọ jẹ.... Wolĩ eke pipọ ni yio si dide, nwọn o si tàn ọpọlọpọ jẹ.

Filippi 3:18, 19a

Nitori ọ̀pọlọpọ ni nrìn, nipasẹ awọn ẹniti mo ti nwi fun nyin nigbakugba, ani, ti mo si nsọkun bi mo ti nwi fun nyin nisisiyi, pe, ọtá agbelebu Kristi ni nwọn: Igbẹhin ẹniti iṣe iparun ikùn ẹniti iṣe ọlọrun wọn....

### *Dariji ki a si dariji Ọ*

Matteu 6:14

Nitori bi ẹnyin ba fi ẹ̀ṣẹ awọn enia jì wọn, Baba nyin ti mbẹ li ọrun yio fi ẹ̀ṣẹ ti nyin jì nyin.

### *Ẹjẹ iyebiye Kristi n ranipada*

I Peteru 1:18, 19 ati 21a

Niwọnbi ẹnyin ti mọ̀ pe, a kò fi ohun ti idibajẹ, rà nyin pada, bi fadaka tabi wura,... Bikoṣe ẹ̀jẹ iyebiye, bi ti ọdọ-agutan ti kò li abuku, ti kò si li abawọn, ani ẹ̀jẹ Kristi;... Ẹnyin ti o ti ipasẹ rẹ̀ gbà Ọlọrun gbọ́.

### *Ẹniti Ẹsẹ n dari*

Isaiah 64:6

Gbogbo wa si dabi ohun aimọ́, gbogbo ododo wa si dabi akisa ẹlẹgbin; gbogbo wa si rẹ̀ bi ewe; aiṣedede wa si mu wa kuro bi afẹfẹ.

### *Ibinu lori ẹmi aigbọran*

Efesu 2:2, 3

Ninu eyiti ẹnyin ti nrin rí gẹgẹ bi ipa ti aiye yi, gẹgẹ bi alaṣẹ agbara oju ọrun, ẹmi ti nṣiṣẹ nisisiyi ninu awọn ọmọ alaigbọran: Ninu awọn ẹniti gbogbo wa pẹlu ti wà rí ninu ifẹkufẹ ara wa, a nmu ifẹ ara ati ti inu ṣẹ; ati nipa ẹda awa si ti jẹ ọmọ ibinu, gẹgẹ bi awọn iyoku pẹlu.

### *Satani ni ọga awọn alaigbagbọ*

II Korinti 4:3, 4

Ṣugbọn bi ihinrere wa ba si farasin, o farasin fun awọn ti o nù: Ninu awọn ẹniti ọlọrun aiye yi ti sọ ọkàn awọn ti kò gbagbọ́ di afọju, ki imọlẹ ihinrere Kristi ti o logo, ẹniti iṣe aworan Ọlọrun, ki o máṣe mọlẹ ninu wọn.

### *Ninu Kristi ni iṣẹgun wa*

Romu 8:1

Njẹ ẹbi kò si nisisiyi fun awọn ti o wà ninu Kristi Jesu, awọn ti kò rìn nipa ti ara, bikoṣe nipa ti Ẹmí.

Matteu 13:38

Oko li aiye; irugbin rere li awọn ọmọ ijọba; èpo si li awọn ọmọ ẹni-buburu ni.

Johannu 8:44a

Ti eṣu baba nyin li ẹnyin iṣe, ifẹkufẹ baba nyin li ẹ si nfẹ ṣe.

***Ninu Adamu, a sọtẹ si Ọlọrun***

Matteu 12:30

Ẹniti kò ba wà pẹlu mi, o nṣe odi si mi: ẹniti kò ba si bá mi kopọ̀, o nfunka.

***Idi niyi ti a fi nilati tun wa bi lọtun pẹlu Ẹmi Kristi***

II Korinti 5:17

Nitorina bi ẹnikẹni ba wà ninu Kristi, o di ẹda titun: ohun atijọ ti kọja lọ; kiyesi i, nwọn si di titun.

Johannu 10:27, 28a

Awọn agutan mi ngbọ ohùn mi, emi si mọ̀ wọn, nwọn a si ma tọ̀ mi lẹhin: Emi si fun wọn ni iye ainipẹkun.

***Yọọda fun Oluwa Jesu nisisiyi***

II Korinti 6:2b

. . . Kiyesi i, nisisiyi ni akokò itẹwọgbà; kiyesi i, nisisiyi ni ọjọ igbala.

I Johannu 1:9

Bi awa ba jẹwọ ẹ̀ṣẹ wa, olõtọ ati olododo li on lati dari ẹṣẹ wa jì wa, ati lati wẹ̀ wa nù kuro ninu aiṣododo gbogbo.

Romu 8:35 ati 37

Tani yio ha yà wa kuro ninu ifẹ Kristi? ipọnju ni, tabi wahalà, tabi inunibini, tabi ìyan, tabi ìhoho, tabi ewu, tabi idà? . . . Ṣugbọn ninu gbogbo nkan wọnyi awa jù ẹniti o ṣẹgun lọ nipa ẹniti o fẹ wa.

I Johannu 5:4

Nitori olukuluku ẹniti a bí nipa ti Ọlọrun o ṣẹgun aiye: eyi si ni iṣẹgun ti o ṣẹgun aiye, ani igbagbọ́ wa.

***Yoo fi ẹbun fun awọn ti o bori***

Ifihàn 2:17, 26; 3:21

Ẹniti o ba li etí, ki o gbọ́ ohun ti Ẹmí nsọ fun awọn ijọ. Ẹniti o ba ṣẹgun li emi o fi manna ti o pamọ́ fun jẹ, emi o si fun u li okuta funfun kan, ati sara okuta na orukọ titun ti a o kọ si i, ti ẹnikẹni kò mọ̀ bikoṣe ẹniti o gbà a. . . . Ẹniti o ba si ṣẹgun, ati ẹniti o ba pa iṣẹ mi mọ́ titi de opin, emi o fun u li aṣẹ lori awọn orilẹ-ède. . . . Ẹniti o ba ṣẹgun li emi o fifun lati joko pẹlu mi lori itẹ́ mi, bi emi pẹlu ti ṣẹgun, ti mo si joko pẹlu Baba mi lori itẹ́ rẹ̀.

***Iwọ se pataki pupọ si Ọlọrun. Kalfari fi eleyi han. Ọlọrun se pataki pupọ si Ọ.***

II Korinti 3:5

Kì iṣe pe awa to fun ara wa lati ṣirò ohunkohun bi ẹnipe lati ọdọ awa tikarawa; ṣugbọn lati ọdọ Ọlọrun ni tito wa.

***Fi ara han pẹlu Kristi ninu ogo***

Kolosse 3:1-6

Nję bi a ba ti ji nyin dide pẹlu Kristi ẹ mã ṣafẹri awọn nkan ti mbẹ loke, nibiti Kristi gbé wà ti o joko li ọwọ́ ọtun Ọlọrun. Ẹ mã ronu awọn nkan ti mbẹ loke kì iṣe awọn nkan ti mbẹ li aiye. Nitori ẹnyin ti kú, a si fi ìye nyin pamọ́ pẹlu Kristi ninu Ọlọrun. Nigbati Kristi, ẹniti iṣe ìye wa yio farahàn, nigbana li ẹnyin pẹlu o farahàn pẹlu rẹ̀ ninu ogo. Nitorina ẹ mã pa ẹ̀ya-ara nyin ti mbẹ li aiye run: àgbere, iwa-ẽri, ifẹkufẹ, ifẹ buburu, ati ojukòkoro, ti iṣe ibọriṣa: Nitori ohun tí ibinu Ọlọrun fi mbọ̀wa sori awọn ọmọ alaigbọran.

***Tabi ki a fi ọ bu lae pẹlu Satani***

Matteu 25:41

Nigbana ni yio si wi fun awọn ti ọwọ́ òsi pe, Ẹ lọ kuro lọdọ mi, ẹnyin ẹni egun, sinu iná ainipẹkun, ti a ti pèse silẹ fun Eṣu ati fun awọn angẹli rẹ̀.

Orin Dafidi 9:17

Ori awọn enia buburu li a o dà si ọrun apadi, ati gbogbo orilẹ-ède ti o gbagbe Ọlọrun.

Marku 9:43

Bi ọwọ́ rẹ ba si mu ọ kọsẹ̀ ke e kuro: o sàn fun ọ ki o ṣe akewọ lọ si ibi iye, jù ki o li ọwọ mejeji ki o lọ si ọrun apadi, sinu iná ajõku.

### *Rẹ ara rẹ silẹ*

Matteu 18:2-4

Jesu si pè ọmọ kekere kan sọdọ rẹ̀, o mu u duro larin wọn, O si wipe, Lõtọ ni mo wi fun nyin, bikoṣepe ẹnyin ba pada, ki ẹ si dabi awọn ọmọ kerere, ẹnyin ki yio le wọle ijọba ọrun. Nitorina ẹnikẹni ti o ba rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ bi ọmọ kekere yi, on na ni yio papọ̀ju ni ijọba ọrun.

Matteu 5:3

Alabukún-fun li awọn òtoṣi li ẹmí: nitori tiwọn ni ijọba ọrun.

### *Ronupiwada ẹṣẹ*

Marku 1:4 ati 14, 15

Johannu de, ẹniti o mbaptisi ni iju, ti o si nwasu baptismu ironupiwada fun idariji ẹ̀ṣẹ. . . . Lẹhin igbati a fi Johannu sinu tubu tan, Jesu lọ si Galili, o nwasu ihinrere ijọba Ọlọrun, O si nwipe, Akokò na de, ijọba Ọlọrun si kù si dẹ̀de: ẹ ronupiwada, ki ẹ si gbà ihinrere gbọ́.

Luku 13:3

Mo wi fun nyin, Bẹ̃kọ: bikoṣepe ẹnyin ronupiwada, gbogbo nyin ni yio ṣegbé bẹ̃ gẹgẹ.

Iṣe 3:19

Nitorina ẹ ronupiwada, ki ẹ si tun yipada, ki a le pa ẹ̀ṣẹ nyin rẹ́, ki akoko itura ba le ti iwaju Oluwa wá.

*(Tẹsiwaju ni oju ewe ti o tẹle.)*

# GBA KRISTI NI OLUGBALA RẸ LONI!

### *Fi ara rẹ fun Jesu Kristi*

Orin Dafidi 37:5

Fi ọ̀na rẹ le Oluwa lọwọ; gbẹkẹle e pẹlu; on o si mu u ṣẹ.

Johannu 3:16

Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẽ gẹ, ti o fi Ọmọ bíbi rẹ̀ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni iye ainipẹkun.

Iṣe 16:31

Nwọn si wi fun u pe, Gbà Jesu Kristi Oluwa gbọ́, a o si gbà ọ là, iwọ ati awọn ará ile rẹ pẹlu.

### *Ọlọrun fun mi ni agbara lati di ọmọ Rẹ*

Ṣugbọn iye awọn ti o gbà a, awọn li o fi agbara fun lati di ọmọ Ọlọrun, ani awọn na ti o gbà orukọ rẹ̀ gbọ́. —Johannu 1:12

### *Jẹwọ Kristi ni gbangba*

Romu 10:9-11

Pe, bi iwọ ba fi ẹnu rẹ jẹwọ Jesu li Oluwa, ti iwọ si gbagbọ́ li ọkàn rẹ pe, Ọlọrun jí i dide kuro ninu okú, a o gbà ọ là. Nitori ọkàn li a fi igbagbọ́ si ododo; ẹnu li a si fi ijẹwọ si igbala. Nitori iwe-mimọ́ wipe, Ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ́ oju ki yio ti i.

Scripture text reprinted from the Bible in Yoruba by permission of United Bible Societies, Africa Regional Center, Nairobi, Kenya.

Published in numerous languages by World Missionary Press as God supplies funds in answer to prayer. If you would like more copies for careful distribution, please write in English to:

**World Missionary Press, Inc.**
**P.O. Box 120**
**New Paris, IN 46553-0120 USA**